# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awọn Alagbara, Ngo si jẹ Alagbawi awọn Odi".—W. T. Stead.

Vol. I. No. 51.     SATURDAY, JUNE 30, 1923.     Fourpence.

### ỌGBẸNI OYINBO F. A. PICKLES

nṣe *Cinema* ni Opopo nla lẹmẹta lọsẹ. Awọ-ṣeju ni awọn aworan rẹ. Iua Manamana ti a si fi nṣe Ẹrọ na mọlẹ bi ọsangangan. Ọrẹ, lọ fi onjẹ oju f'oju nibẹ. Ẹmẹta lọsẹ lo nṣe e *Monday, Wednesday* ati *Saturday*, ni agogo mẹjọ abọ alẹ (*8.30 p.m.*)

---

### A. KESSLER,

Ile owo Oyinbo German Hamburg.

Iwọ le ranṣẹ Ẹrọ-Iransọ "*Mundlos*" ati "*Adler*" nibẹ bẹ si ni Ẹrọ-riran bata pẹlu.

Ẹ tọ Ọgbẹni A. Kessler lọ ni 7 Labinjọ Lane, koro Williams Street.

**Mundlos on top Mundlos.**








A nranṣẹ orisiriṣi ọja fun enia o tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*

Ọja tiwa ya. A si ni ọja wọnyi fun tita:—Ohun ẹrọ orin, Awo-Abọmafọ, Kọkẹ-ologere t'Ọkunrin t'Obinrin, Waji

Ẹ le ri Ẹrọ Iransọ "*Mundlos*" ra lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati lọdọ H. Campos ti Campbell Street.

**Mundlos on top Mundlos.**

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

Undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

PRICES ON APPLICATION

to

S. I. M. Johnson,
6, Scale Square,
Phone 227 Lagos.
P.O. Box 408.

---

ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "Excelsior" ni Ita Agarawu, ni onirurú awọn ohun ẹlẹkọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O n ṣowo lọri Iṣẹ loriṣiriṣi lati adọta ọdun sẹhin titi di ọ n.

ATAKI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn oniṣowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tito wa ni owo pọ o.

---

ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONISOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni oriṣiriṣi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, oniṣowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni
No. 44, Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:– Ikoko taba, Carpets Panu ikole, Aṣọ oniruru, Itẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yomini, (*Satten*.)

Ati oriṣiriṣi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Oniṣowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrèmèrè onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà nibẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office :* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor.*

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

ẸLA L'ORỌ.

O dun ni pupọ lati gbọ pe ọrọ ti a sọ nipati *Lawyer* ko ṣe *Lawyer* l'ọsẹ to kọja ba ọpọlọpọ enia ninu jẹ, pāpā awọn *Lawyer* wa ni ilẹ yi. A fẹ sọ fun gbogbo enia pe ko si ohukohun ti ẹnikọkan ninu wọn fi ṣe wa ti yio fi di ogun a nsọrọ wọn ni aidára; ati pe Eko nibi kọ ni ohun ti a sọ fun wa na gbe ṣẹlẹ. Nitori eyi, a tọrọ gafara gidigidi lọwọ awọn *Lawyer* wa na ti a gbọ pe ohun ti a sọ na bi ninu nitoriti o da ni loju pe nwọn ko jẹ hu irufẹ iwa ti a sọrọ rẹ yi.

A si ṣe kilọkilọ yi fun awọn enia Agbọ-t'eku-wi-f'ẹiyẹ ki nwọn ye foju daṣọ fun awọn enia alaiṣẹ-alairò ró, nitori ọrọ yi.

Lẹhin ohun ti a wi yi, ẹnikẹni to ba tun mọ̃ l'ẹwa to ba yãn run nipa fifi ẹnikẹni ṣe yẹ̀yẹ́ nitori ọrọ yi, ti oluwarẹ ba lọ ri idin ni'yọ̀, ko kan wa o! ! !

"EKO AKETE" ND'ỌKỌNRIN MẸTA.

*Saturday* t'o mbọ ni yio di ọdun kan gbako ti a ti bẹrẹ si ṣe Iwe-Irohin "Eko Akete"!

A ni'reti pe awọn ọkawe wa, awọn ọrẹ, ati ojulumọ wa, ati awọn ẹlomiran yio ranti ati pe wa l'enia ni akoko nla na.

ỌBASA NṢE OHUN ARA.

A gbọ pe Ọgbẹni D. O. Ọbasa ti Ibadan npete ati bẹrẹ si titẹ Iwe-irohin kan, ninu oṣu to mbọ.

AWỌN IJỌ BROTHERHOOD NDA NKAN NI'DE.

Gẹgẹ bi a ti sọ ni ọsẹ to kọja Isin akanṣe ti awọn Ijọ *Brotherhood* fẹ ṣe ni iranti ọdun mejidinlogoji ti a ti bi *Pastor* A. Adedeji Iṣọla ẹniti o da Ijọ na silẹ larin wa nibi ni ọdun 1918, yio bẹrẹ lọla. A o ni Isin Adura ati orin ni Ile-Isin wọn Ilupesi ni agogo meje abọ arọ Ọgbẹni Olukọya Ọnabanjọ Olori Ẹka Ijọ yi ni Ijẹbu Ode ni yio ṣe Alakoso Isin yi.

Ni alẹ ọla ni agogo meje Prof: Adeoye Deniga yio ṣe Iwasu Akanṣe nipa Ọjọ-Ibi yi nibi kanna: gbogbo enia la pe si Isin yi t'arọ ati t'alẹ.

Ni ireni (*Tuesday* t'o mbọ) a o ṣe Ipade Nla ti gbo-gbo-gbõ nibi kanna, gbogbo Ijọ Brotherhood yio si fun Pastor A. Adedeji Iṣọla ni Iwe Iyẹsi ati Ẹbun ti o to tun. Dr. Oguntọla Ṣapara I.S.O. ni yio ṣe Alakoso Ipade na. A o bẹrẹ ni agogo meje alẹ. A pe gbogbo Ọrẹ ati awọn Ojulumọ si ibi Ajọyọ yi.

ATẸ ILẸKẸ FẸ DI ATẸ ỌRUNLA?
KA MA RI! KA MA RI!!!

Ni ọjọ diẹ sẹhin a gbọ pe ọkan ninu awọn Oni'we Irohin nibi kọwe si awọn Ọlọpa lati gba Iwe Ọti fun tita, ati pe awọn Ọlọpa kò jẹ ọhẹn si Iwe Ọgbẹni na,

EJI DE, EJI MA DE O BI-NSA.

Ojo to rọ ni *Saturday* to kọja "bu-a-ya" ṣaṣa ni awọn enia ti ko pọ lẹhin lati lọ sibi iṣẹ ni'jọ na; gbogbo ode lo kun fun àgbàrá, ni adugbo miran bi Ọnala, àgbàrá ibọ gba ọkọ wete, A gbe pe omi ya si gbangan Ile Dr. Jones

ogiri ile pętęsi kan si wo ni 19 Williams Street, șugbọn a dupẹ pe ko pa ẹnikẹni lara.

A! MA PE IGBA RẸ NI TIRẸ; YIKA LA NRI DOJE IKU, O NB'ẸGBẸRUN LULẸ!!!

Irohin iku ojiji Ọgbẹni kan ara Saro ti a npe ni Black kan ni ninu ọsẹ yi. A gbọ pe ko pẹ t'o ti Onitsha bọ wa sibi, to si haya Ile kan ni No. 74 Ita Bamgboșe ko ju iwọn oșu kan lọ to de ile yi, a si sọ pe o ti san owo asan silẹ fun ile na fun oșu mẹrin. A gbọ pe iba ba ọkọ *Appam* lọ si ilu rẹ ni ọsẹ to mbọ lati lọ fi ara mọ iya rẹ lẹhin na ki o si lọ si *England*. Șugbọn lai beni-beji, Ọlọjọ de!!! Ki Baba tu opo rẹ ninu ati Iya pẹlu awọn ibatan rẹ miran.

Kini ẹmi nyin?

A-BẸSIN BI OKE, Ẹ KU ORI'RE.

A ba Ọgbẹni J. Alẹșinlọyẹ Williams ti No. 2 Ofin Road nibi, yọ fun ọmọkunrin kan ti obinrin rẹ fi ta a lọrẹ ni *Thursday* Ọsẹ to kọja.

Ẹ kabọ, ọmọ Af'ẹșin șa'na.

ỌLỌLA NI ỌLA NYẸ.

A gbọ pe awọn *Doctor* yio șe ariya kan fun Dr. Oguntọla Șapara ni Ile Afari Ogun ni *Wednesday* ọsẹ t'o mbọ lati ba yọ ayọ Ọla ti Ọba king da a ni lọlọyi nipa oye I.S.O. ti a fi bun u.

Ire a kari o.

OYINBO ABERIN FA NI MỌRA!

A gbọ pe Ọgbẹni Oyinbo R. S. Jameson Onișowo ti Opopo nla (*Broad Stree*) npete ati lọ si Ilu rẹ (Ilu Oyinbo) ninu ọkọ *Appam* ni ọjọ kẹfa oșu to mbọ lati tubọ lọ mu owo pupọ wa si i fun awọn ara Eko gẹgẹ bi ișe rẹ.

Ọgbẹni Oyinbo yi jẹ Ọlọyaya pupọ ninu wọn Oyinbo Onișowo, ko si jẹ kanra sọ ẹnikẹni, ibașe enia dudu tabi funfun ninu awọn to ba wa sọdọ rẹ nipasẹ ọrọ owo.

Awa papa le jẹri si eyi pe Ọmọluwabi fanfau ni Oyinbo yi, opọlọpọ ni eri musẹ rẹ ti fa mọra, ti nwọn si di ipa bẹ jẹ onibara rẹ. Ọkọ a re fo o.

Ẹnikẹni to ba fẹ kọwe si Oyinbo na, le șe bẹ nipa kikọ si itọju *The Colonial Bank*, 4 Adopheplaty, Hamburg tabi Grace Church Street London pẹlu owo ilelẹ ati irepe ọja (*Samples*) iru eyiti nwọn ba fẹ.

## IJA DOPIN, IREPỌ DE.

IROHIN NIBA ȘOKI.

ỌDUN "AGBA"

Awọn ọmọ-ọmọ Ọlọto bẹrẹ ọdun "Agba" ni Ọto ni *Saturday* to kọja, ọjọ kẹsan oșu *June* yi. Gbogbo ẹsẹ wọn lo pe si igbo imọlẹ nibiti nwọn lọ pa obi.

Agogo mẹfa kọja ișeju mẹdogun Ọgbẹni Akilolu Akodu ati Ọgbẹni Ọtẹniya Bașọrun lo șiwaju awọn to lọ tẹsẹ bọmi nigba mẹta, bi ișe dalẹ wọn. Ọgbẹni Akisanya Mọgaji duro ni igbo abọrẹ o nșe etutu bi arira, o si nmi aja bi nwọn ti nbọ wa kansẹ fun. Awọn obinrin ti ọmọde ti agba lo nșe igbe tele wọn lẹhin bi nwọn ti nlọ ti nwọn nbọ; igbe na ndun yungba.

Niwọn agogo mẹsan imọlẹ bẹrẹ si ke. Nwọn nda agba kikankikan. Wọn si șere titi mọju nipa așẹ awọn onilu.

Mo ba awọn ọmọ-ọmọ Ọlọto yọ pupọ. Adura mi fun wọn nipe așeyi șe amọdun—*Așe*.

Oluwa majẹ ko bajẹ. Șugbọn enia nșe ko bajẹ, ki wọn bale yọ, kole bajẹ o.

ỌMỌ-ALAGBA-ỌLỌTỌ.

## IGBA NI ONIGBA I KA!

Inu wa dun lati ri pe Aluta J. A. Cole B.A. ti Ijọ St. Peter bẹrẹ isin li ede Gesi ni *June* 3, ni agogo mẹfa abọ. Ohun ti o fi wasu ni Orin Dafidi 122, 1. "Inu mi dun nigbati nwọn wi fun mi pe, ẹ jẹki a lọ si ile Oluwa."

Kọ daju pe nwọn șe isin ede Gẹsi nibẹ ri, ibẹrẹ didun yi si fihan pe iyoku yio ma dara. Awọn akọrin si kọ Orin Dafidi 18 daradara.

A nireti pe laipẹ nwọn yio forikori lati kọ *Church* titun ti nwọn ti nfara lati akoko Alufa E. J. Ṣowande ologbe, a woye pe aye ŋha pupọ fun ọpọ enia pẹlu. Ẹnyin enia Ijọ, ẹ maṣe jafara rara. Alufa ko ni ipa kan kan ẹnyin li ẹ nṣe e, ẹnyin ti ẹ nṣe bi ṣolo bi ṣala ninu Ijọ na, a ri nyin, a ki nyin, ko ni rẹ nyin, ohun akọtun rere bayi na li a o ma ri titi o. Alufa, maṣe jafara o, iṣẹ de, ki o mura ki o sin iran tirẹ o. Gbere, Ọmọ-Liṣabi mo gbadun iwasu rẹ na kẹ! A ri eyi na o! A kan sara si ọ pẹlu ọkan mimọ ni o.

ỌLAREWAJU.

---

## Open Letters.

To Celebrities, Notorities, etc., in Defferent Walks of Life.

No. 24.

To His Honour,
SIR. RALPH COMBE Knt.
Chief Justice,
Lagos. Nigeria.

Your Honour,

Knowing as I do your large heart and broad sympathies not less than your strict sense of duty, it wi[ll], I take it, grieve you to learn that under present arr[a]ngement, by which litigants living in certain parts not remote from the Law Courts in town are [m]ade to attend to their law-suits in The District Court of Ebute-Meta much inconvenience is caused in this community.

Under this Order, I am told that the jurisdiction of the latter Court extends from Ebute-Ero to the very heart of Tinubu Square, and goes on to Broad Street with a terminus at Oke Olowogbow[o] !!!, also that European Firms doing business in [the] block are exempt from its operations.

Very recently, the case of a gentleman whose residence is in juxtaposition with the Law Courts at Tinubu and whose application for a civil summons against another party who also lives within a stone's throw to the Judiciary was reported to me; the applicant being directed to Ebute Meta before his wants could be met in spite of the fact that Tinubu Court-house is AT HIS VERY DOOR!!!, thus he was allowed to starve in the midst of plenty.

I cannot conscientiously congratulate the Government on the bungling business, which to my mind shows neither foresight nor system and the sooner the Order is rescinded the better will it be for all concerned.

This anomaly need only be brought to your notice, and I am sure it is a foregone conclusion that necessary RELIEF will follow.

Eko Akete.

## *Empire Day, 1923.*

### IṢẸ TI ỌBA ILU GẸSI RAN SI AWỌN ỌMỌDE.

—:o:—

Awọn iṣẹ ti Oba ati Ayaba Ilu Gẹsi ran lati inu ẹrọ olorin (*Gramophone*) ni a fi ranṣẹ si ibi gbogbo ninu Ijọba, ki awọn ọmọ Ile-Ẹkọ le gbọ wọn ni Ọjọ Empire. Awọn iṣẹ na niwọnyi :—

*IṢẸ TI ỌBA RAN.*

Loni, gbogbo awọn enia Mi nibi gbogbo l'aiye papọ lati yọ ayọ iṣọkan wọn, ati ki nwọn si tubọ mu ki okun kan na ti o jọ so wọn pọ sunmọ ara wọn pẹkipẹki. Olukuluku ninu ogunlọgọ awọn enia wa li o ni igbe-aiye tirẹ lati gbe, olukuluku si ni iṣẹ tirẹ lati ṣe, sibẹ gbogbo wọn jẹ ọmọ idile kan, ibanujẹ ati ayọ, ọkan si ni ibanujẹ ati ayọ ekeji. A ti fi kọ nyin bi o ti jẹ pe awọn akin, ati ọlọgbọn enia l'ọkunrin ati l'obinrin ti igba lailai li o pilẹ Ijọba yi. Ohun ti o si le mu ki a wa pẹ titi ko ju igboiya, ọgbọn ati aimọ-kiki ti ara ẹni nikan tabi ki a maṣe ni ẹmi temi ṣa lọ. Ogun ti o tobi ni, Awọn baba nyin ati awọn baba nla nyin li o ṣiṣẹ rẹ silẹ. Nipa Ipese Ọlọrun, ọwọ nyin ni alafia ijọmiran, ati orukọ rere Ijọba na wa.

Ẹ maṣe ro o bi ohun ti o jina rere si nyin. O kan olukuluku nyin, ohun gbogbo ti ẹ ba si ṣe tabi ti ẹ ba le kọ nisisiyi ni yio sọ asọtẹlẹ bi ẹ o ti fi tẹyẹtẹyẹ ṣe ipa ti nyin si nigbati ẹ ba dagba.

Ẹ ni inọ, ẹ jẹ akin, ọlọla, ati oninu rere, ẹ ma ronu ọmọnikeji nyin ṣaju ki ẹ to ronu ẹnyintikara nyin, ẹ si ma fi ṣe iwa hu nigba gbogbo.

Ọna bayi li ẹ o fi ṣe ara nyin yẹ lati fi iru iwa bẹ le awọn enia Ominira Ọrilẹ-ede yi, awọn ọmọ nyin ati ọmọ-ọmọ nyin lọwọ, bi ohun elo nla nla fun ododo, alafia, ati ifẹ inu rere, eyiti araiye yio ma yẹsi, ti nwọn yio si ma gbega pẹlu.

*IṢẸ TI AYABA RAN.*

Loni ọjọ iranti ati ireti yi, ti isi ṣe ọjọ-ibi Ayaba Victoria ayaba rere ni, iṣẹ ti mo ran si nyin li eyi, ẹnyin ti ẹ jẹ ọmọlọwọ idile agbaiye wa fun awọn orilẹ ede ati awọn enia gbogbo. Igba gbogbo ni ki ẹ ma ronu ohun ti ẹ le ṣe lati jẹki ile nyin ni ayọ, ati ọna ti o darajulọ ti ẹ le gba lati mura ara nyin silẹ ki ẹ le kọ ile ayọ silẹ de iran awọn ọmọ nyin ti yio tẹle nyin. Ninu Ijọba nla wa yi, ọpọlọpọ ile li o wa ati ọpọlọpọ oniruru aṣa. Ile ibiti a ba gbe ntọju ọkan mimọ ati ọkan ti o ninu rere ni Tempili Ọlorun, ẹmi ile rere, iba ṣe ti talaka tabi ti olowo jẹ ọkan ninu ohun ti o darajulọ l'aiye. Ọpọlọpọ ẹkọ ni ẹ le kọ ni Ile-Ẹkọ, ti yio ti nyin lẹhin lati jẹ ọlọgbọn ati ara ilu ti o wulo ninu Ijọba ti Gẹsi, ṣugbọn ko si ohun ti ẹ le kọ, ko si si ohun gunmọ ti ẹ le ṣe fun ara nyin ati fun

gbogbo enia ti inu idile nla ti Gesi yi ju ẹkọ ti o rọrun julọ, ti ile, inu rere ati aimọ ti ara ni enikan, eyiti iṣẹ agbara ati ẹwa igbe-aiye enia, iba ṣe ni-ba ibanuje tabi ni, ba inu didun.

**EKO AKETE.**

Eko, Saturday, June 30, 1923.

## B'OKU FẸ BI KO FẸ, Ẹ WA WO ỌMỌ OLOKU LODE.

O jẹ ohun to dun mọ ni pupọ lati ri pe lati igbati Ijọba ti fi yiyan enia si Ajọ Igbimọ Aṣofin lọ gbogbo ilu lo nko kẹkẹ fun ipalẹmọ ọjọ nla na; orişirişi Ipade ni a si nşe lati fi ohun ribiribi yi ye awọn enia wa o si jẹ ohun ti o fun ẹnikẹni ni işiri gidigidi lati ri pe awọn Ẹgbẹ Ilu (*The Ilu Committee*) ti a le pe ni baba fun awọn Ẹgbẹ Şọlọ-şọlọ-şọlọ to ku lo kọkọ bẹrẹ işẹ na, nipa Ipade agbayanu kan ti nwọn şe ni Ile Afari Ogun lẹhingbẹti ninu oşu yi ti ile kun ti ọna si fi bò; gbogbo ipade wonyi lọtun losi ko le şe ko ma tẹmbẹlu ede adakandeke awọn kan ti nwọn sọ ni iwọn ọdun ti koi pẹ yi pe, awa ara Eko ko ni mọ iyi anfani nlanla yi bi Ijọba tilẹ fi lọ ni tobẹ ti nwọn fi mu Ẹka Ẹgbẹ *Congress* ibi l'ọta nigbana, ti awọn enia t'a nwi yi (Nwọn ko sai mọ ara wọn) si fi nhuwa pe "kàkà k'eku ma jẹ sèsé a fi ş'awa danu," nje a bi nyin ẹnyin ara wa B'oku fẹ bi ko fẹ ẹ ko ha ri ọmọ oloku lode? ẹnu wa ko gbọ̃rọ̀ lati şọpẹ lọwọ Ijọba wa ti ko bù ọrọkọrọ awọn enia na wo, şugbọn gẹgẹ bi baba, ti nwọn si gbọ adura wa nipa fi fẹfi anfani enia yiyan na dan wa wo lọdun yi; a si mọ pe awọn enia wa ki yio dojuti Ijọba nipa aimọ riri ohun kà-nkà-ká-nká na, eyi lo si mu ki gbogbo ilu ma ja rariyin fun fifi ọwọ si iwe ti awọn ti o to sọ oju abẹ ni'ko ati yan enia (*Voters*) nfi ọwọ si, eyiti a si nfi ranşẹ si Sẹkitẹri "Ọgba Munisipa" gẹgẹ bi a ti lana rẹ silẹ; oni nikan lo ku ti a sọ pe gbogbo awọn iwe fi f'ọwọ si na ni lati pari, a si bẹ awọn enia wa iyoku ti nwọn ni ẹtọ ati yan enia şugbọn boya ti nwọn ko iti fi ọwọ si Iwe tiwọn lo nwọn ma şai jigiri ati şe bẹ. Ẹnyin ara ilu, Ẹ jọwọ, Ẹ şe akikanju si ọran ti-an-ti-an yi, ki ẹ ma si jẹ ki awọn ti a le pe ni ajeji larin wa nibi gba işe wa şe loju wa (ọrọ diẹ ni ti ọmoluwabi, ki o ma ye nyin o) "L'aiku ẹkiri tani jẹ fi awọ rẹ se gbẹdu?"

O dọwọ olukuluku wa o, ki a ma ri ẹniti yio fi ọrọ na şe yọbọkẹ, ki Baba gb'ọwọ wa o. Aşẹ.

---

## MUSICAL EVENING AT U.N.A. CHURCH

[*By an Observer.*]

On Friday June 22, 1923, I attended a Service of Songs for Harvest time held by Jehovah Shalom Church Choir. The service began at about 7 45 p m. instead of 7 30 p.m. as announced in the Notice. There was a fairly good number of choristers on the choir stall. After the opening hymn and prayer, Mr. C. B. Williams sang a solo; he in his usual melodious voice commanded my attention and left no room for want. Mr. C B. Williams appeared in an Evening Dress, as one of the partakers on the occasion he was exepected to appear in choir robes amongst the choristers, but this was not so, I understand for certain reason. Mrs Antus Williams took part at the service and was found in the coy of choristers. The part alloted to her was quite appropriate "All is Beautiful," it was beautifully rendered. Amongst the items of programme, there was only one duet and was rendered by a soprano and a contralto; it seemed to be the best of all other items and was very well rendered. The boy that sang the soprano part deserves merit, if he is given a fair training, he may likely become one of the best sopranos in the African Communion. Judging the average ability of the choir, the performance of the evening was successful, although from musical standpoint, some of the songs were not very interesting. The frequent Bible reading suffered the service to become lukewarm, despite a few well-known hymns that were included which the congregation heartily joined occasionally.

The Organist should be congratulated upon his efforts which contributed to the success of the evening as the result of his patient labour. I think a word of advice may do him some good. I advise he should learn the use of harmonium stops and should not in future content himself with a set of stops from start to finish. He should note carefully and act on the direction of musical degree. He should keep as far as possible the same time with the choir, and lastly should not the accompanying part to cover the choir when singing or whenever a solo is being rendered.

The Service was brought to close at 9 p.m. with benediction.

---

## ẸBẸ FUN INA MỌNAMỌNA NI OPO-PO ỌJA ITOKU ATI ṢAPỌN, NI ABẸOKUTA.

To the Editor, "Eko Akete,"
Lagos.

Ogbẹni Alagba,

Inu mi a dun bi o ba gba mi l' aye diẹ lati sọrọ meji tabi ju bẹ lọ sinu Iwe-irohin rẹ yi, ti ọrọ ifojusun rẹ lọ bayi:—

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunmu han awọn Alagbara, ngo si jẹ Alagbawi awọn Odi." A dupẹ lọwọ Oniwe-irohin yi pe, gẹgẹbi ọrọ ifojusun rẹ, bẹni o ri. Iwaju ni k Ọpa Ẹbiti rẹ ma re si o.

Inu ọpọlọpọ ninu awa ti o jẹ ọrọnyan fun lati ma gba ọna ti o dide lati ọja Ṣapọn ni Ita Ọṣinlẹ, ti o wa si ọja Itoku, yio dun, bi awọn Baba wa ti o nṣe 'lu ba ba onina Mọnamọna wa *Electric Lighter* sọ, ki o le ma tan 'na ti o wa ni ọna ti a darukọ rẹ yi:— Ṣapọn, Itoku Market Main Roads. O ṣa jẹ ọna pataki fun Igboro wa, o si ni P. T. O. awọn opo ina.

Ki Ọba wa jọwọ ye, ki o ma ṣe jẹ ki o rẹ on, ki o ma si ṣe fi eti si ọrọkọrọ ti awọn alaimọkan miran nsọ si i, Ọlọrun yio wa pẹlu rẹ gẹgẹbi o ti wa pẹlu Mose ati Jọṣua pẹlu Dafidi ati Solomon, awọn Baba nla wa, pẹlu awọn Igbimọ rẹ.

A ko ṣe alairi ilọsiwaju ti o wa n' Ilu wa yi nisisiyi, a fi owo ti o ṣ'ọwọn ati iṣẹ, eyi ki i ṣe ibikan "Ibigbogbo ni a 'sa nko adiẹ alẹ!" Oluwa yio mu ayipada rere wa s' Ilu wa na o. Amin!

Mo dupẹ lọwọ rẹ, Oniwe-Irohin "Eko Akete," fun aye ti o gba mi.

Emi ni tirẹ nitọtọ,

FRANCUS.

Abẹokuta,
16/6/23.

---

## ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Amulu-mala li o pọ ninu awọn orin ti a nkọ ni ohun ilẹ wa, diẹ l'a le ri ti o jẹ ti awọn ilẹ wa san-san. Nihin o yẹ ki a kan sara si Alabọjuto Ijọ Brotherhood fun iwe-orin ti Ijọ rẹ ti o jade ni iwọn oṣu diẹ sẹhin; ọpọlọpọ ohun orin inu iwe na ni o jẹ ti awọn ilẹ wa, lorisirisi, awọn ọrọ orin na si kun fun akin ati ẹkọ l'oniruru ọna.

A nfẹ orin ni ohun ilẹ wa, eyiti bi o ba ti ta si olurekọja l'eti, yala Imale tabi Abọriṣa, yio le tọka irufẹ ohun orin na, ati orilẹ ti o jẹ mọ.

Apọn ti awọn atẹduru wa nṣe ni sa yi ni pe ki nwọn joko lori aga Duru lati ma ra baba lori ọmọ ika Duru (*Key-board*) ki nwọn le mu orin jade ni ohun ilẹ wa, lọpakọna ti ọkan wọn ba tẹ si i. Ọkan ninu orin bẹ ti mo ṣalabapade lọ bayi:—

*m* : *m* — | *s* — *s* | *d* — *m* | — — — |
*d*' : *d*' — | *l* — *l* | *s* — — | — — — |
*m* : *m* — | *s* — *s* | *r* : *m* : *d* | — — — |
*m* : *m* — | *r* — *r* | *d* — — | — — — |

Tani le ka orin yi si ọkan ninu ohun orin ilẹ wa. Orilẹ-ede wo lo ni irufẹ ohun orin tọ lọ bayi,—*Wi ki ngbọ*.

OYENẸYẸ.

---

## *IN MEMORIAM.*

In loving Memory of my dearly-beloved father

FAṢEKẸ OLUKOLU

Who departed this life at his residence
Idumagbo, Lagos,

*On the 27th June, 1906.*

He is not dead
Whose glorious mind
Lifts thine on high.
To live in the hearts of those we leave behind
Is not to die.

By his son,
BỌLAJI.

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alaworan | ... | 3d. |
| Iwe Alaworan Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alaworan Keji | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sà kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nsisiyi, a si le ri won ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ogbọn ẹniti o ti je olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *sare nbaja*.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

---

## IN MEMORIAM.

In loving memory of

ỌMỌWUNMI COLE

*Died 29th June, 1922.*

"Death, be not proud, though some have called thee,
Mighty and dreadful, for thou art not so;
For these whom you think'st thou dost overthrow,
Die not, poor Death; nor yet canst thou kill soul,
From rest and sleep, which but thy picture be,
Much pleasure; then from thee MUCH MORE must flow,
And soonest our best men with thee do go,
Rest of their bones, and soul's delivery.
Thou'rt slave to fate, chance, kings, and desperate men
And dost with poison, war, and sickness dwell,
And poppy or charms can make us sleep as well,
And better than thy stroke. WHY SWELLEST THOU, then?
And short sleep past, WE WAKE ETERNALLY;
And death shall be no more: DEATH, THOU SHALT DIE."

"L' orọ ọjọ Ajinde wa
'Boji yio m' oku rẹ wa;
Baba, Iya, Omo, Ara
Y'o pade"

ỌNỌṢOKUN.

---

## ADUPẸ ỌJỌ.

Ọgbẹni Dada Adegigbin ati awọn Aburo rẹ dupẹ fun gbogbo awọn ọrẹ ati ojulumọ ti nwọn ba wọn daro ni orişirişi ọna nigbati baba wọn ṣe alaisi ni ọjọ keje oṣu yi.

Ki Ọlọrun fi ọmọ rere kẹhin gbogbo wa o!

## IGBẸ L' OWO WÀ.

### LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ỏwỏ wọnyi ti gba Ọja *(Produce)* l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£16—£16 10 fun *ton* kan

### EPO.

£25—£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

### COCOA.

£27—28 fun *ton* kan bakanna.

---

### KANO—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—£14 10 per ton
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

---


## DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the moderu and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

---

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa orişirişi ko ni egbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni **A.** BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onişowo to nranşẹ ọja fun tita lati ilu ọba ( *England* ) wa. O si ma nfi ọja şọwọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranşẹ ni wọnyi :—
Gẹdu, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo. Obi, Igi Osun, Agbado, Iwo Malu, Awọ orişirişi.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranşẹ fun lati Ilu Ọba ( *England* ) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aşọ orişirişi, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn oşişẹ wa ko le şe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oşisẹ ilẹ wa ko le şe iru rẹ.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki işe ti asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi şe tabi ẹyiti o jẹ onidẹ ( Brass )

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranşẹ si nyin nibikibi ninu *Motor Transport.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (Morning)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(Evening.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

Morning. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
Evenning. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

**WESLEYAN**

10.30 a.m. Tinubu
7 p.m. do.
10.30 a.m. Ereko
7 p.m. do.
10.30 a.m. Olowogbowo
7 p.m.
10.30 a.m. Ọbun Eko
7 p.m.

**AFRICAN (COMMUNION)**

9 a.m. Jehovah Shalom
7 p.m. do.
9 a.m. Erelu
7 p.m. do.
9 a.m. Bethel Rev. E. A. Akinola
6.30 p.m. Bro. J. B. Coker
9 a.m. Zion
6.30 p.m. do.
10.30 a.m. African Methodist
4.30 p.m.

**FIRST BAPTIST CHURCH**

10.30 a.m. Bro. R. O. Macaulay
6.30 p.m. Rev. J. R. Williams
9 a.m. Ararọmi (Baptist) Rev. A. A. Puddicombe
4 p.m. do.

**EBENEZER (BAPTIST)**

9 a.m.
6.30 p.m.

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. Ilupesi Bro. Olukọya Ọnabanjọ
7 p.m. Prof. Adeoye Deniga
(Special Sermons on Founder's Day)

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon; Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

Seservic at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Campbell Street Open Air Service
John P. A. Taylor, Wm. C. T. Terrel

---

Messrs. J. R. Thomas & Sons of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices. This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refresh ment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*. 1504

## N. V. Handlemattschappij V.H.

J. E. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laiijü, l'eti *Glover Memorial Hall.* (*Customs Street.*) EKO





Awọn Oyinbo Onisowo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikeni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-irohin yi ra lọdọ Asoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ogbeni VIDAL R. COLE.

## Sorinolu's Grammar School.

*The first ever Established in Abeokuta and Ije Ode since 17 years ago.)*

All Grammar School Lesson efficiently taught t Advantage and Success.

*Tuition Fees Rated by the Readers :—*

Primers 1 and 11—3/- *per Quarter.*
Readers 1 to 111—3/- *per Quarter.*
Readers 1v and v—6/- *per Quarter.*
Classes 1 to 111—9/- *per Quarter.*
Boarding Fee—£1 2s 6d. Monthly.

This is beside the Tuition Fee; and includes, Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services.

PLEASE NOTE!

Payments strictly in advance; otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYO SORINOLU,
Iporo Ake, Abẹokuta. *Principal & Proprietor.*

## The Philharmonic Band.



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si

*THE SECRETARY,*
c/o Aafani Motors
The Marina Lagos.

## JACOB A. AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

JUNE 30


## ALASE LEATHER FACTORY.
### "ILE ALAWO."

Awo ẹsẹ bata (*sole-leather*) ti a ṣe daradara, ti o lẹ ti o si pupa yo, ati Awo Hausa ni orisirisi awo, yala ni pupa, funfun, dudu, oféfe, ati orisi awọ miran ni a nta ni ọpọku ọyọku.




Bi o ba fẹ wa wo Ile Awọ nla yi, ti iru rẹ ko si ni *Nigeria*, bi bẹkọ kọwe ṣọwọ pẹlu owosi :—

E. B. BEYIOKU-ALASE
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*. —Alawọbata, Eko.

## "O ṢE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ogbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orisirisi oja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ojo oja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan aro, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun ẹnia. Mu ọja rẹ lọ sibẹ.

## All for Bicycles and Motors.

Ask for KADUNA STORE,
No. 81, Ọdunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.
*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Beaded-edge 12/-
do. do. 15/-

The above Tyres are specially for Rudge-withworth and German Cycles and we have complete workshop for repairing of all kinds of machinery. Send all your repairs' Bicycles, Motors, Sewing machines, Gramophone, painting, enamelling work soldering, etc., to the Properitor at the undermentioned address. All Bicycles spare parts on sale.

SAM. A. CLAY,
No. 1 Macauley Street,
or at Workshop, 81, Ọdunfa St.
Lagos.

*Telegram Address:*—KADUNA STORE,
81, Ọdunfa Street,
Lagos.


## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete."

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja ninu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu Iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.